# ILE IGBIMỌ ASOFIN IPINLẸ ỌYỌ
## ORILẸEDE NAIJIRIA

IGBIMỌ ILE KẸJỌ
IPELE KEJI
NỌMBA KẸFÀ

## IWE EETO

### Ọjọ́rú Ọjọ́ Kẹta Osù Kẹjọ Ọdún

1. Adura
2. Fifi ọwọ si Iwe Akọsilẹ ati ifẹnuko ijoko Ọjọ Ọjọ́ Iṣẹ́gun, Ọjọ́ Kejì, Osù Kẹjọ, Ẹgbẹ̀wá Ọdún Le Mẹ́rìndínlógún
3. Isẹ lati Eka Alase
4. Ifilọ
5. Ẹbẹ ati Lẹta
6. Idari
7. Ọrọ Pataki Gbogbo'gboo Ti O Jẹ Pajawiri
8. Alaye Olorijori

---

### ILANA ISẸ TONI

9. **GBÍGBA ÀSAYÀN ORIN ÌPÍNLẸ̀ ỌYỌ́ GẸ́GẸ́BÍ OHUN ÌDÁNIMỌ̀ PÀTÀKÌ:**

OYHAB/08/45/16 Kí Ilé ṣàgbéyẹ̀wò àsàyàn orin Ìpínlẹ̀ Ọyọ́ láti mọ rírì ìwúlò rẹ̀ pẹ̀lú èróngbà láti gba gẹ́gẹ́bí ohun ìdánimọ́ Pátákí tí a ó maa kọ ní gbogbo àpéjọ Pàtàkì ní Ìpínlẹ̀ Ọyọ́ – Asòfin A.M. Adéyemọ (Ìla Oòrùn Ìbàràpá) – Alága Ilé

10. **ṢÍṢE ÀMÓJÚTÓ ÌWÀ ÀÌGBỌRÀN NÍ ILÉ ẸKỌ́ WA ÀTI WÍWÁ ỌNÀ LÁTI DÁ ÈTÒ ẸKỌ́ TÓYÈ KOORO TIÍ SỌ AKẸ́KỌ̀ DI ALÁṢEYỌRÍ ATI ỌMỌLÚÀBÍ PADÀ NÍ ÌPÍNLẸ̀ ỌYỌ́**

OYHAB/08/46/16 Kí Ilé jíròrò lori àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tó nṣẹlẹ̀ ní ilé ẹ̀kọ́ alákọbẹ̀rẹ̀ àti girama ti Ìjọba tí múkí iná ẹ̀kọ́ jó àjórẹ̀hìn àti bí àwọn akẹ́kọ̀ kan ti gbé ìwà ìbàjẹ́ wọ̀ bí ẹ̀wù, pẹ̀lú èròngbà láti rọ ẹ̀ka aláṣẹ láti gbé ìgbésẹ̀ làti mú ètò ẹ̀kọ́ ní ọ̀kùnkúndùn – Asòfin Òkunlọlá Silas Adélérè (Ìwájọ̀wà)